WEEKS 25&30


| |
|---|
| WEEKS 25&26 |
| Kongi WK 25 |
| 19, 20, 22 |
| WK 26 |
| 2 4 8 |
| Asiko Bks Wk 25 |
| 28 31 32 38 |
| WK 26 |
| 14 15 26 27 |
| ROSS WK 25 |
| 2&30 |
| WK 26 |
| 12&23 |


THE ED. FOR IMOLE OWURO
15/1/77
IBADAN.


# Imọlẹ Owurọ

EṢIN ỌRỌ WA: IMỌLẸ DE OKUNKUN PARADA!


UNITY NAP
For 3 sure bankers for week 26 send ₦5 to E. O. Adeyẹmi c/o P. M. B. 5230 Ibadan. OR come to Imọlẹ Owurọ Office Ib.

**8, 18, 22 nap**



Independent Paper Vol. XV NO 781 SATURDAY JANUARY 15—FRIDAY JANUARY 21, 1977 10K. (KOBO MẸWA)


# OGA OLOPA MEJI ṢIṢẸ DA GBẸSẸ

AWỌN Ọlọpa meji ninu Ọlọpa ilẹ Naijiria, ti ṣiṣẹ Ọlọpa di gbese ẹgbẹjọ Naira (₦1,600).

Pẹlu tulaasi ni awọn gbọdọ fi sanwo na fun Ọba ilu kan ti iṣẹ Olọko Oko ni Kansul Irẹpọdun ni Ipinlẹ Kwara. Ripẹtọ kan wa ninu awọn Ọlọpa na.

Awọn Ọlọpa na ni: Ọgbẹni Eki ati Ọgbẹni Mathew Oroko.

Ọba ti a wi yi, Ọba Jọṣua Ogundinde Yọyinoye ni o pe awọn Ọlọpa meji na l'ẹjọ sile ẹjọ giga ilu Ilọrin pe, nwọn ti oun mọle lai ba ofin mu ninu oṣu kẹfa ọdun ti o kọja.

Ninu ẹjọ na ti agbẹjọro Ọba na, Ọgbẹni Peter Ọlọrunniiṣọla pe l'orukọ ẹlẹjọ rẹ, o ni ni ibẹrẹ oṣu kẹfa ọdun 1976 ti o kọja yi ni Ijoye kan nilu Oko ti o jẹ Oloye Olọwa ilu na, tọ awọn Ọlọpa lọ nile iṣẹ Ọlọpa Omu-Aran pe, oun ri nkan ofin ninu oko Ọba na.

Agbẹjọro na so pe l'ori eyi ni eyi ti o jẹ Ripẹto ninu awọn Ọlọpa na ṣe paṣẹ fun Ọlọpa keji rẹ; Ọgbẹni Mathew Oroko lati lọ mu Ọba na wa ni aafin rẹ ni Oko.

Siwaju si i, Agbẹjọro na sọ pe, nigbati nwọn mu Ọba na de ago olopa nwon bo aṣọ kuro l'ara rẹ, nwon si ju u si itimole awọn Ọlọpa nipa aṣẹ Ripẹto Eki.


(Woju Ewe Kẹjọ)


## ABỌDE ILU OYINBO

ALHAJI OLOWONYỌ

NUMBER OKLP 65

EYI ni lati sọ fun gbogbo enia pe, lagbara Ọlọrun, ni ọjọ Alamisi ti iṣe ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu kinni ọdun yi (27/1/77) ni a o bẹrẹ si i ta rẹkọọdu titun ti gbajumọ ati olokiki alare Kunmi System nni, Alhaji Fatayi Olowonyọ ati awọn Ẹgbẹ alare Gita ibilẹ ṣẹṣẹ ṣe nipa iriinajo abọde ilu Oyinbo ti o ṣe l'ọdun ti o kọja.

Awo rẹ titun na, eyi ti nọnba rẹ jẹ OKLP 65, pabanbari, o koyọyọ. Are araọtọ ni nwọn ṣe sinu awo na pẹlu orin agbọdunnu.

Ara awọn akọle inu awo na niwọnyi:

OJU KINNI

1 Abọde Ilu Oyinbo
2 Akinsọji Mọdele
3 Orin awọn Ọta
4 Wosilatu Abẹkẹ

OJU KEJI

1 Ọrọ Ojowu Obinrin (Apa Keji)
2 Wọn w'ẹran t'o tobi to Erin,
3 Ẹ tẹriba fun agba
4 Mo gunyan lẹbẹ
5 Ẹgbẹ Ifẹlodun Muṣin.



OLOWONYỌ

Irohin ko to afetigbọ ni awọn are inu awo na; koṣeemani ni fun gbogbo ẹni ti o nfẹ amunudun ninu ile.

Tete lọ ṣeto silẹ pẹlu oluta rẹkọọdu ti o wa ni adugbo rẹ.

Distributor:
OGO OLUWA KIITAN
TRADING COMPANY LTD.
128, Agege Motor Road,
Atẹwọlara, Muṣin
Telephone 46252.
Tabi ni ẹka wonyi
*51, Railway Line
Odi—Olowo, Muṣin.
*119, Herbert Macauley St,
Ebute—mẹta
*2, Badejo Street,
Agege, Lagos State.

## Gomina Ogun nkeko si i



S. A. Balogun
Gomina Ipinlẹ Ogun

GOMINA Ipinlẹ Ogun Ọgagun Seidu Ayọdele Balogun, ti kọja lọ si Jaji ni Oke-Ọya nibi ti oun ati awọn Ọgagun-Ọgagun miran ninu ọmọ ogun Naijiria yio takẹkọ tẹsiwaju ninu iṣẹ Ogun.

Oṣu mẹfa gbako ni nwọn yio fi kẹkọ na.

Bayi, Ọgagun Aliyu Mohammed ni o ndele de Gomina na, o si ti bẹrẹ si i ba iṣẹ na lọ ni gbara bi onitọhun ti ngbesẹ.


## Apprentices Wanted

LEARN to become a successful printer; learn on modern machine with modern technique.

Parents, don't waste the time of your fresh Primary Six & Modern III School leavers; send them to learn modern printing, Machine operating and Book-binding from us. Apply personally today.

The Works Manager,
(Imole Owuro)
N4/496B Yemetu Aladorin,
Ibadan:


## 'Sara tori Olo'un' d'eewo

IJỌBA Ipinlẹ Ọyọ ti so o l'ofin pe lati igba yi lọ; ẹnikẹni ti ko ba to ọmọ ọdun mẹtadinlogun ko gbọdọ maa ṣagbe kiri mọ.

Ninu ikede ti Ijọba na gbejade ni ilu Ibadan ninu ọsẹ yi, o lodi si ofin fun awọn ọmọde na lati maa ṣagbe kiri.

Ikede na sọ pe iru eni bẹ ko gbọdọ torọ.


(Woju Ewe Kẹjọ)

# ATIORO OMO ATIALA

## Ma dan an wo (14)

Ko s'eni t'Oluwa da
Ti ko l'ẹbun l'aiye;
Onikaluku l'aiye
L'a ran nişẹ
Pe, ko fi ş'aiye nire;
Şugbọn ọpọ enia
L'o nşi tire ẹ lo.
Ọtọ l'ẹbun ahọn,
Ọtọ l'ẹbun işẹ ọwọ,
Ọtọ l'ẹbun işẹ ọpọlọ;
Ọtọ si l'ẹbun iwa.
Ẹni t'o l'ẹbun ahọn,
Oun l'a f'agbara fun
Lati maa fi
Ahọn wọn tun
T'ọmọ araiye şe;
Awọn l'enia
Ti i gba ni n'imoran;
Awọn ni i kọ ni lọgbọn.
Awọn ni i şe iwaasu,
Awọn ni i şe sato
Ti i tun ile t'o daru şe;
Awọn l'o ni ẹbun ironu
Awọn l'o l'ẹbun ọrọ,




Awon l'a fi ran
Lati tun aiye şe
Awọn l'enia
Ti i fi iriri aiye
T'ori ọmọ elomii şe.
Nj nitorina, iwọ enia
T ngbọ Nasia yi:
Bi a ba fun ọ l'ẹbun
ahọn
O yẹ ki o şora gidi;
Ma fi ahọn ba t'ẹda jẹ,
Nşe ni o maa fi şaato
Nitori a kuku ti ri
Awọn ẹni a fi fun
Ti nwọn fi b'aiye jẹ:
A r'opọ enia
T'o n'iru ẹbun yi
T'o fi nhuwa ẹşẹ
Ọpọ ti bugada
O fi ba t'ẹda jẹ;
Ọpọ fi tirẹ
O fi ndẹşẹ kiri;
Ọpọ enia ewẹ
L'o fi nşi ẹda l'ọna
Ọrẹ, bi o ba n'iru ẹbun
yi,
Dakun, ma fi şe
Biliisi f'ẹnikan
Nitori:
B'o ti wu ko jinna to,
Aala yio beere
Bi o ti lo ẹbun ohun si;
Je k'o da ọ l'oju pe,
Ọlọrun Ọba t'o fun ọ
Yio beere
Ohun ti o fi şe,
Yio si san ẹsan iwa
F'ẹni t'o fun l'ẹbun.
Nitorina;
Ma f'ẹbun rẹ şe 'bi ọ,
Ma dan an wo.
Nitori, mo ti r'ọpọ enia
T'Ọlọrun Ọba da
T'o şe l'ẹlẹnu t'o muna,
Mo si r'enia ẹwẹ
T'o fi şuga si l'ete;
Mo ti r'enia
T'Oluwa fun l'ọgbọn
T'o jẹ pe,
Bi ile ba fẹ tuka,
Yio f'ọrọ enu tun un
şe;
Mo si r'enia
Ti i fun ni n'imoran
T'aiye t'o buruja
Fi le pada l'ayọ.
Şugbọn ọrẹ,
Iwọ ni mo nbi leere;
Bawo l'o ti lo o si ?
Bawo l'o ti lo
Ẹbun ọro sisọ
T'Oluwa fi ta ọ l'ọrẹ ?
Eke l'o fi nşe
Tabi idaluru ?
Enia l'o fi nşi l'ọna
Tabi o nlo o
Lati f'ori agbo meji
Bọ koto horokan ?
O fi nto ile ni
Tabi o fi ntu ile ?
O fi nto ilu,
Tabi o fi ndaluru ?
O fi npari ija
Tabi o fi ndajasilẹ ?
O fi nşe rere
Tabi o fi nşika ?
O fi nşişẹ mimọ
Tabi o fi nşaimọ ?
O fi nko ba mi
Tabi o fi nko ni yọ ?
O fi nlujibiti
Tabi o fi nşetọ ?
O fi nba t'enia jẹ
Tabi o fi
Ntun t'enia şe ?
O fi nşorẹ enia
Tabi o fi nşọta enia ?
O fi ngbòrukọ
Oluwa Ọrun ga
Tabi o fi nfi
Abuku kan orukọ
Ọga Ogo t'o da ọ ?
Iwọ enia pata
Ti ngbọ Nasia yi;
Ewo l'o fi nşe o
Ewo l'o fi nhu niwa ?
Maa ro o titi ọsẹ t'o
nbọ

Nitoripe:
Ọrọ koi tan l'ori eyi,
Nasia ku niwaju.
ỌLỌLA ATIORO

# Adelebo njejo esun ole

AWỌN Ọlọpa ilu Warri ni Ipinlẹ Bendel ti fa obinrin abileko ọmọ ọdun mẹtadinlogun kan wa sile ẹjọ Chief Magistrate ilu na lati koju ejo ẹsun ole.

Orukọ obinrin na ni Christiana Johndy ti abule Ephan lẹba Warri. Awọn afẹsunkaani fi ẹsun kan obinrin na pe, ni ọjọ kẹfa oşu kejila ọdun ti o kọja ni ọdaran na yọkẹlẹkẹlẹ wọle Obinrin kan ti nwọn npe ni Mary ni abule Ephan, o si ja a lole.

Awọn afẹsunkanni sọ pe, adelebọ na ji aşọ iro mẹẹdọgbọn ati awọn gele ti gbogbo rẹ to ẹgbẹta Naira; ati pe o tun gbe igba Naira ninu ile obinrin na.

Bakanna ni nwọn fi ẹsun kan obinrin na pe, o wọle obinrin miran ti njẹ Alice Obibi ni Okere, o si gbe e ni aşọ iro marunlelọgbọn ati gele ti apapọ iye owo rẹ jẹ ẹgbaa Naira (₦2,000).

Irohin fi ye wa pe, konko ni obinrin na şoju nigba ti o farahan nile ẹjọ.

Ile ẹjọ ko ti i maa ba ẹjọ na lọ; şugbọn ile ẹjọ gba iduro rẹ ni ẹẹdẹgbẹta Naira ati oniduro kan.

# Iyarele Ikirun jade l'aiye

Nwọn ti kede iku Iyarẹlẹ Ikirun, Arabinrin Ọmoboye Arinkẹ ni agbole Ebipọlọgba, Oke Amọla nilu Ikirun.

Aadọrun ọdun ni nwọọ sọ pe o lo l'aye; ọpọ ọmọ ati ọmọ-ọmọ l'o si gbẹhin rẹ.

Ọpọlọpọ enia ni o wa sibi isinku ologbe na.

## Best Four

# 3
# 10
# 26
# 41




NIGERIA NEW STATES CO.

jẹ atẹwe asiko. Bi o ba fẹ tẹ oniruuru iwe: Kalẹnda, Almanak ati bẹẹbẹẹ lọ, Ile Işẹ wa ni:

18, Ọdunlami Street,
Phone 27017, Lagos.



WOLI S. I. OWOẸYẸ
Oniwaasu Naa.

# Akede ọna Iye

ONAKANSOSO SI IYE AINIPEKUN

# E MAA YIN OLUWA Logo

"Ẹ maa yin Oluwa. Ẹ maa yin In ẹnyin iranṣẹ Oluwa. Ẹ maa yin Orukọ Oluwa. Ibukun ni Orukọ Oluwa lati isinsinyi lọ ati titi lailai:" Orin Dafidi 113; 1—2.

Gbogbo ẹnyin enia ti nbẹ ninu aiye l'oni ni mo nke si: Ẹ dide, ẹ jigiri; ẹ jẹ ki a fi iyin fun ẹni ti iyin yẹ fun ani, Ẹni ti O da Ọrun oun Aiye ati gbogbo ohun ti nbẹ ninu won—Ọlọrun kan ti aiye ati ọrun nbẹ ni ikawọ Rẹ.

Gbogbo ohun ti ngbọ ohun Oluwa l'aiye ati l'ọrun: ẹ maa yin Oluwa l'oni; nitoripe, iṣẹ Oluwa tobi, agbara Rẹ nikan l'o si le gba ni. Ododo Oluwa duro lailai.

L'oni, gbogbo ẹnyin ti o ni ibẹru Oluwa ni ọkan: Ẹ maa yin In l'ogo nitoripe, ẹnyin ni Baba rere, ani Ọlọrun.

Nitoripe, Ọrọ Oluwa tọ; gbogbo iṣẹ Rẹ ni otitọ. Nipa Ọrọ Oluwa ni a da awọn Ọrun ati gbogbo ogun wọn nipa eemi ẹnu Rẹ.

Njẹ l'oni gbogbo aiye, Ẹ maa yin Oluwa l'ogo. Gbogbo aiye, ẹ bẹru Rẹ. Nitori Oluwa sọrọ, o ti ṣẹ. O paṣẹ, o si duro ṣinṣin.

Ẹnyin ogun Ọrun: Ẹ sọkalẹ wa sinu aiye l'oni. ẹ maa ba mi yin Oluwa l'ogo. Omi oke ati omi Isalẹ; ẹ maa yin Oluwa l'ogo. Imọlẹ t'o wa s'aiye, ẹ maa yin Oluwo l'ogo. Ọsan, ẹ yin In l'ogo; aṣaalẹ: ẹ yin Oluwa l'ogo;

Aṣaalẹ, ẹ yin Oluwa l'ogo; oru, ẹ yin Oluwa l'ogo ofurufu, ẹ yin Oluwa l'ogo. Iyangbẹ ile, ẹ maa yin Oluwa l'ogo; Omi okun, ẹ maa yin Oluwa l'ogo; imọlẹ ofurufu Orin, ẹ yin Oluwa l'ogo; imọlẹ to tobi ti nṣe akoso ọsan, ẹ maa yin Oluwa l'ogo. Imọlẹ t'o kere ti nṣe akoso oru, ẹ maa yin Oluwa l'ogo.

Aiye atijọ, ẹ ba mi yin Oluwa l'ogo; aiye isinsinyi, ẹ ba mi yin Oluwa l'ogo. Aiye lati atetẹkọṣe, ẹ maa yin Oluwa l'ogo; aiye ti yio wa lailai, ẹ maa yin Oluwa. l'ogo

Gbogbo ẹnyin enia ti ẹ nsọrọ l'oni, ẹ maa yin Oluwa l'ogo. Gbogbo ẹnyin alaisan, ẹ jẹ ki ọkan nyin, maa yin Oluwa l'ogo nitoripe oku ko le yin Oluwa, alaaye ni yio yin In l'ogo.

Agbara Oluwa duro lailai; imọ Oluwa yi aiye ka. Ẹ fi Ogo fun Un ẹnyin ọmọ alade. Ẹ fi Ogo fun Oluwa ẹnyin ọmọde; ẹ fi Ogo fun Oluwa ẹnyin agbagba. Gbogbo ọjọ, ẹ maa yin In l'ogo. Ọba ti O le sọ pe, ki o wa ti yio si wa ti o le sọ pe, ki o lọ ti yio si lọ. Ọba Alaṣẹkanṣoṣo l'aiye ati l'ọrun. Ọrọ Nla t'o ngbe inu ọmọ enia fọhun. Ọba Nla ti ki I sun. Ọba t'o ngba talaka lọwọ iya.

Ẹ jẹ ki ohun gbogbo t'o li ẹmi yin Oluwa l'ogo. Ẹ yin Oluwa gẹgẹ bi titobi nla Rẹ.

Ogo ni fun Ọlorun l'Oke Ọrun. Aleluya! Aleluya !!

## Lati Owo Woli S. I. Owoeye

## IWE ỌRỌ ỌLỌRUN

Fun anfani ẹnyin ti o ṣoro fun lati ri iwe mi yi ra ni ọkọọkan, mo ti ṣeto lati maa fi apapọ iwe na ṣọwọ si nyin ni aadọta Kọbọ (50k) pere.

1. ADURA AIYERAIYE
2. IBANIWI OLUWA
3. KINI ILE AIYE ṢE BAJẸ ?
4. Ẹ JỌWỌ ARA NYIN FUN OLUWA

Bi o ba ti fi Postal Order 50k ṣọwọ si mi, ng o fi apapọ iwe na ṣọwọ si ọ lagbara Oluwa. Fi owo ranṣẹ si:

Woli S. I. Owoẹyẹ,
Box 1206,
Ibadan.

# Ẹgbẹ Imọlẹ Owurọ

12,392 John O. Akano, Igbo-Ọra

12,393 Oseni Owobọmọjẹ, Ẹdẹ

12,394 Ọmọniyi Ismaila, Okeya

12;395 Saidu O. Salawudeen, Omugo

12,396 Jimọ B. Lawal, Agbeye

12,397 Gbadegẹṣin Ọlatunji, Ibadan

12,398 Mary Ladokun, Ibadan

12,399 Law-Ayẹni Dọtun, Ibokun Ileṣa

12,400 Mathew Alẹ—sinlọyẹ, Omupo

12,401 Saliman Yufuf, Ogbomoṣọ

12,402 Alhaji D. Agẹṣinkari, Ibadan

FUN IGBEGA EDE ATI AṢA YORUBA
DI

**Omo Egbe Imole Owuro**
(Iwe Idi Ọmo Ẹgbẹ)

Oruko rẹ ____________________

Adirẹsi rẹ ____________________

Ọmo ilu ti o jẹ ____________________

Jawe yi ki o si poosu rẹ si
DOKUN AJADI
(Akowe Ẹgbẹ)
P.M.B. 5230, Ibadan

## ADEDEWE FUN TITA

EYI ni lati sọ fun gbogbo enia ti o ti nbeere iwe ADEDẸWẸ ti Ọgbẹni Lawuyi Ogunniran kọ pe a ti ni fun tita bayi.

Gẹgẹ bi ẹyin na ti mọ, iwe na kọ ni lọgbọn pupọ o si yẹ ki olukuluku enia ni lọwọ ati ọmọde ati agba, paapaa o dara lati fi tọ ọmọ ẹni sọna.

50k ni ẹyọkan, fi owo oniyekiye ti o ba fẹ ra ṣọwọ si:

Alufaa Yisa Igbaẹlode,
N2/394A Odoye,
Adeọyọ Road,
Box 3365,
Ibadan.

# Irohin ni Onilujilu

## IRAGBIJI

ALAGA Ẹgbẹ awọn oluko ni Ipinle Ọyọ, Ọgbẹni J. A. Adewale ti kesi awọn oluko jakejado ilẹ Naijiria lati fowosowopọ nipa riran aṣoju ẹka kookan wa lati mu ki ipade ajọ nla ti gbogbogboo Ẹgbẹ na l'agbaiye, eyi ti yio waiye nilu Eko ninu ọdun yi yọri si rere.

Ọgbẹni Adewale pe ipe yi ninu iṣẹ ọdun titun ti o ran si ọpọlọpọ Oga ile iwe Alakọbẹrẹ ti nwọn pade ni Gbọngan ilu Iragbiji laipẹ yi.

Ọgbẹni Adewale ran awọn enia na leti pe o ṣe pataki lati dawo Ẹgbẹ wọn, eyi ti o sọ pe Ẹgbẹ yio fi gbe eto ajọ nla na joko. O ni Naira mejimeji ni Tiṣa ti owo oṣu rẹ ba wa labẹ isanwo GL.O7 ati ju bẹẹ lọ.

Ṣiwajusi i Alaga na rọ gbogbo olukọ lati tubọ jara mo iṣẹ wọn ki eto ẹkọ ọfẹ alakọbẹrẹ aiye le yọrẹ si rere.

Ni ipari, Alaga na mu un da gbogbo olukọ Ipinlẹ Ọyọ loju pe, Ẹgbẹ oun yio maa wa ire wọn nigbagbogbo.

## JOS

IROHIN lati ilu Jos ni Oke—Ọya fi ye wa pe, laipẹ yi ni Ọgbẹni Sam Ladeji Ajao ṣe ikomọjade ọmọkunrin kan ti Ọlọrun fi ta oun ati aya rẹ lọrẹ.

Orukọ ti nwọn sọ ọmọ na gẹgẹ bi ilana ẹsin Onigbagbọ ni, Mathew Ọlatunde Ajao; awọn obi ọmọ na si fi jijẹ ati mimu tẹ awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na l'ọrun.

Ọpọ enia ati ẹlẹgbẹjẹgbẹ ni o wa lati Bukuru ati Kano.

Ara awọn alabaṣẹyẹ ni Moses Ọlatunji, D. A. Ọyatẹru, J. A. Adediji, David Akanni, S. A. Adedokun, C. A. Akanbi E. O. Babalọla, Aderintọ Adelẹyẹ, Sam Ọdẹjobi, E. F. D. Alade Timothy Afọn, D. A. Alaṣoro, David Ajagbe,- Joseph Adelakun, Moses Ayangunna, ati Joseph Ayanwọle.

## ABEOKUTA

NI ọjọ 'Bọ ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi ni awọn Kansilọ Igbimọ Ijọba Ibilẹ Abẹokuta ni Ipinlẹ Ogun ṣe ipade akọkọ, ninu eyi ti nwọn yan Alaga wọn.

Awọn enia mẹta l'o du ipo Alaga, ṣugbọn ẹni ti awọn Kansilọ fi ibo gbewọle ni Alhaji Wahabi Ailẹru ti o jẹ gbajumọ kan ni ilu na, ẹni ti o ri ibo mọkanla ko.

Awọn enia meji ti o ba du u ni Oloye Samuel Ajala ti o ri ibo mẹjọ ko ati Oloye Ade Ọyalọwọ ti o ri ibo mẹta ko.

Ninu ọrọ rẹ fun ipade Igbimọ titun na, Ọgbẹni A. O. Ọnabokun ti iṣe Akọwe Igbimọ Ijọba Ibilẹ na, ẹni ti o kesi awọn Kansilọ na lati maṣe ja awọn ti o dibo fun wọn ni tanmaa.

Akọwe na rọ wọn lati ṣiṣẹ wọn ni otitọ ati ododo, o si ṣe ileri pe Ijọba Ipinlẹ Ogun yio ti wọn lẹhin.

## AKURE

BIŞỌỌBU Ijọ Aguda fun ẹkun Ondo, Ẹni-ọwọ Francis Alongẹ, ti kesi awọn ọdọ ni ẹkun na lati wa kẹkọ fun iṣẹ Alufaa.

Laipẹ yi ni Bişọọbu na pe ipe yi ni ilu Akurẹ nigbati o nwaasu nibi igbọwọlelori Ẹni-ọwọ Joseph Dayọ Akinjo gẹgẹ bi Alufaa titun. Ni ile ijosin ti njẹ Sacred Heart Cathedral nilu Akurẹ ni isin na ti waiye.

Bişọọbu Alongẹ sọ iṣẹ Alufaa si Bişọọbu ati si Ijọ enia Ọlọrun; ati pe, o si gbọdọ maa fi apẹẹrẹ rere lelẹ pẹlu gẹgẹ bi aṣaaju Ijọ.

Nigbana ni Bişọọbu Alongẹ kan saara si awọn obi Alufaa titun na fun yiyọọda ọkan ninu ọmọ wọn lati kẹkọ di Ojiṣẹ Ijọ Ọlọrun.

Ni ọjọ kejidinlogbọn oşu kẹwa ọdun 1949 ni a bi Alufaa Akinjo. O kẹkọ nile ẹkọ ikọṣẹ Alufaa kekere ti njẹ Sacred Heart Mirior Seminary nilu Akurẹ ati ni ile ẹkọ ikọṣẹ Alufaa nla ti njẹ Saints Peter and Paul Seminary ni adugbo Bodija nilu Ibadan.

**40**


# GBANGBA ẸWA!

N405.00



GBANGBA EWA—Alupupu Suzuki A100

Fun agbara ti ọ ni, ati igbẹkele ti o ki—GBANGBA ẸWA—SUZUKI A100
Fun irọrun ati ewa ti o gbamuṣe—
GBANGBA ẸWA—SUZUKI A100.
O ni agbara pupo, ko si iye ti o ngba fun itoju.

Ko sirọ nibẹ, alupupu
Suzuki 'A100' jẹ GBANGBA ẸWA

SUZUKI Ra ohun to yẹ ọ.

# ÌSỌ̀RỌ̀-N'ÌGBÈSÌ...

## IPADE (39)

Lawuyi Ogunniran
A dupẹ ọdun eşin kọja;
Ọmọ Aiişegiri:
A dupẹ t'ọdun eyi tẹle e
T'o tun ş'oju wa;
A dupẹ t'a a r'ọdun yi
Baba Kafilatu
Too, ọmọ Ajişegiri
Ọdun titun l'o de yi,
Oo le şe, taboo le şe?
Adeyẹmo Ọjẹrinde
Iru şişe wo l'o nwi ọmọ Ejigbọjọ?
O sa kuku mọ pe,
Mo n'iyawo sile,
Mo tun nşana omiran titun,
Mo si ni majeşin
Ti nlọ si Sukuru.
Taileşe ti jẹ ?
Lawuyi Oguniran
Ajao, ma şi mi gbọ
Ng ko sọrọ alufaasa;
Ng ko si şawada.
Ohun ti mo nbi ọ ni pe,
Ọdun titun t'o de yi
Şe, o ti şetan?
Şe o ti gbaradi?
K'a maa ba faaji lọ?
Eyi ni mo nbeere
Ti *o* fẹ sọ d'ọrọ awada.
Adeyẹmọ Ọjẹrinde
Ng ko mọ p'eyi l'o nwi ọmọ Ejigbọjọ
Ki l'o nş'oju ọjọ?
Ki l'o nşe mi
Ti ng ko lee şe?
Mo ti gbaradi lat'eşin
Lati maa b'ọrọ wa lọ ninu ọdun titun;
Bi o ko ba ni i şawawi,
Mo ti şetan ibeere.
Lawuyi Ogunniran
Maa bi mi l'ohun o ba fẹ;
Ọmọ Ajişegiri;
B'Ẹlẹda ba fẹ,
Ng o da ọ lohun gbogbo
Ayamọ b'o ba şe
Ohun ti ko l'esi ọrọ.
Adeyẹmọ Ọjẹrinde
Nigba ti o nsọrọ laipẹ
K'a too pari ọdun;
O sọ fun mi pe.
Iwọ ki i ş'alaroye şa bi ẹiyẹ ọpẹẹrẹ;
Bawo l'o şe mọ pe,
Aroye şa l'ọpẹẹrẹ nşe lai gb'ede ẹiyẹ ?
Bawo l'o şe le tabuku
Pe, gbogbo'hun t'o nsọ ko wulo ?
Njẹ, o ko mọ pe
Ibalorukọjẹ l'eyi jẹ ọmọ Ejigbọjọ?
Njẹ o ko mọ pe,
Iwa ẹẹ l'eyi f'awọn ọpẹẹrẹ asiko?
Şe, b'o ba şe p'ọpẹẹrẹ le şe e,
Nşe l'o yẹ ki nwọn pamọpọ
Ki nwọn f'oko ọrẹ mi jẹ;
Ki gbogbo ata t'o ni
T'o fi nşowo di jijẹ;
Ki gbogbo ibẹpẹ roboto
K'o di bibomọlẹ;
K'ọpẹẹrẹ Ibadan kọwe
K'o pe t'*O*gbomọşọ;
Ki ti Sokoto gbọ,
K'o ranşẹ pe ti Kutuwenji;
Ki t'ilẹ Aganyin wa
K'o ranşẹ si ti Niger,
Ki gbogbo wọn gbogunde
Ki nwọn f'oko ọrẹ mi mi jẹ
Nitori ede abuku
T'o nsọ s'ọmọ ẹiyẹ lai şẹ——
Lawuyi Ogunniran
Ajao, o to; jẹ ng f'esi sọrọ rẹ:
Nitootọ ni mo wi.
Mo nsọrọ l'oju enia godogodo;
Atontori ẹiyẹ lasan
Ti nbẹ ninu oko;
Koda, b'o ş'ogidan,
B'o ş'aritọgbaju;
Ko si babanla ẹranko
T'o le ke mọ 'ru wa
Nitori pe, enia l'ọga
Fun gbogbo ẹda ti ndọwọdelẹ
At'eyi ti nfaiyafa.
Şugbọn l'ori ọpẹẹrẹ ti o wi,
Alaroye şa l'ọpẹẹrẹ,
Aroye rẹ ko jẹ nkankan;
Aroye ti ko kọ ẹda l'ọgbọn
L'o nbẹ l'ẹnu rẹ l'ọpọ igba
Ajao! Ş'o ngbọ, ọmọ Ajişegiri;
B'o ba şe pe a rọgbọn kọ
Ninu ohun ẹiyẹ ba nwi,
Ki l'o de t'a a lee fara we ẹiyẹ oko ?
Şugbọn kini k'a ti gbọ 'ru eyi
P'eeyan nf'ara we alaroye oşi ?
Nitorina, ọmọ Ajişegiri:
Jẹ k'o lọ ye ọ pe,
Ng ko parọ m'ọpẹẹrẹ
Ng ko si ba a l'orukọjẹ.
Bi mo ba tilẹ ba a l'orukọjẹ,
Ki l'ọpẹẹrẹ o fi 'ru awa şe ?
T'ifọnnu kọ, t'ihalẹ kọ,
Ẹgbẹfulẹ ọpẹẹrẹ ko le de mi l'ọna;
Bẹẹ babanla ẹiyẹ oko
Ko lee jẹ wa l'oko run;
B'iwọ paapaa si d'ọpẹẹrẹ,
Awọn majẹşin ti nbẹ l'oke ẹgan wa
Ni yio ş'ọkọ fun ọ,
Nwọn o ju oko lu ọ,
Nwọn o ta ọ ni rọba danwo.
Adeyemọ Ọjẹrinde
A! ọmọ Ejigbọjọ!
O si nf'asọdun bẹrẹ ọdun titun!
T'awọn ẹiyẹ oko l'o fẹ ri gbamu
O bu enia ko to,
O tun nş'eleşu lẹhin ẹiyẹ oko!

L. Lawal Bankers
12
29
33

IWE IGBAẸLODE DARA PUPỌ, RA TIRẸ NIBẸ
1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati *Agba* 20k
2. Kurani ọgọta esu ni ede Yoruba N10 Esu kan (50k)
3. Yasin ni Yoruba ati Isawaka 50k
4. Zabura ati Itumọ (N1)
5. Zabura Yoruba (N1)
6. Iwe Aiye Akamara (N1)
7. Iwe Eniaşoro (N1) Adedẹwẹ (50k)
8. Iwosan Ajẹbidan Ogun enia dudu (N5); Kekere (75k)
9. Iwe ala ni ala (N2)
10. Kekere (50k)
11. Iwe Oogun iwosan (N2 - 50) Kekere (75k)
12. Itan Anabi ati Yisa (N1)
13. English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (50k)
FI OWO ATI STAMP (5k) RANŞẸ SI:
1) Alufa Yisa Igbaẹlode N2/394a Odoye Adeọyọ Rd. P. O. Box 3365, Mapo—Ibadan.



(2) Alufa Igbaẹlode, Mọşalaşi Idi-Işin St, Isalẹ Koto P. O. Box. 17 Ilorin

3 5 7 9

133745

# Ijo Onilekeu dupe lowo Larubawa

NI ojo Satide ti ise ojo kejo osu kinni odun yi ni awon Egbe ti · da ilekeu sile ni apapo Ipinle Oyo, Ondo ati Ogun dupe lowo Asoju Ijoba Larubawa ni ile Naijiria fun ebun opolopo Tira ti nwon fi ta awon ile keu na l'ore. Ni ilu Iwo ti ise olu ile ise Egbe na ni nwon ti se ayeye-idupe na.

Ninu oro re nigba ti o nko awon Tira na fun won, A s o j u na, Abdur Rahamoni Rasheed H u w a e n i ati enikeji re Abdul Rasheed Adiatu, kan saara si awon omo Egbe na fun ilakaka w o n lati gbe esin Islam ga.

O ni Ijoba oun ko nii bojuwehin lati maa ran won lowo paapaa laipe yi nipa ebun owo ati fifi oluko ranse si won gege bi ibeere ti Egbe na gbesiwaju awon.

Asoju na dupe lowo Egbe na fun apoale ti nwon se fun awon; o si so pelu pe, awon ko nii gbagbe lailai.

Ara awon enia gidi ti o pese sibi ayeye na ni

## Ara Efon binu jale

I R O H I N lati ilu Efon Alaaye ni Ipinle Ondo, fi ye wa pe, nse ti awon ara ilu na kojale gbangba lati lowo ninu ibo Kansilo ti o koja lo yi.

A o ranti pe, awon ara ilu na ti n h a l e saaju ojo ibo na pe, bi Ijoba Ipinle na ko ba fi ilu Efon-Alaaye se olu ile ise Kansul iha Iwo-Oorun ile Ekiti, awon enia ilu na ko ni i dibo l'ojo idibo Kansilo ti o waiye jakejado ile Naijiria ni ojo kejidinlogbon osu kejila odun ti o koja.

Awon ara ilu na so pe lati bi odun mejidinlogun wa ni Efon ti je olu ile ise Kansul na; ti pe ireje ni o je fun enia Efon nigba ti Ijoba Ipinle Ondo kede pe Aramoko ni olu-ile ise Kansul na yio wa.

Eyi ni o mu ki nwon taku patapata ti nwon ko si dibo yan Kansillo kankan ni ilu na; awon nikansoso ni ko ni Kansilo bayi.

# KI L'O SELE?

Igbakeji Imam Iwo, Alhaji Mudasiru Iyalade, Alhaji Salawu Motokese, Alhaji Usamotu Kuta, Alhaji L. A. Sanni, Alhaji Basorun, Alhaji Mudasiru Aliyu, Alhaji A. B. Mohammed, Alhaji Ibiyemi, Alhaji Oyewale, Alhaji Salawu, Alhaji Asimi Kelani, Alhaji Akintayo, Alhaji Oriolowo, Alhaji Taliatu Tela ati Isiaka Raheemi pelu Suleaman Badiru.

## Agbomojo di Baba ibeta

NI ojo ketalelogun osu kejila odun ti o koja ni Olorun fi omokunrin meta ta Alhaji J. A. Agbomojo ti ise Oniwaasi Musulumi kan nilu Ibadan l'ore.

Ni ogbonjo osu na ni nwon so awon omo na loruko ninu ile baba omo na ni adugbo Nalende nilu Ibadan gege bi ilana esin Islam nibiti awon ore, ebi ati alabaseye pese si

Ara awon asaaju esin Musulumi ti o s e t o isomoloruko na ni Alhaji belo Akanji Mukadamu ti ise okan ninu Alufaa Egbe Shamusideen. Awon yoku tun ni, Alhaji Esin ni-yiobiwa ti ise Asaaju Ijo Sumuratu Suaday.

Oruko ti n w o n so awon ibeta na ni, Wahabi Aremu Jimo Agbomojo, Abudul Rahamoni Alabi Jimo Agbo—mojo ati Abudul Rabimi Akanmu Jimo Agbomojo

Ninu oro re n i b i isin isomoloruko na: Alhaji Mukadam se ikilo pe ko si omo kekere jojolo kan ti i so fun awon obi re pe, epo tabi ata tabi iyo ni ki o maa ta; tabi pe ki awon obi oun maa sagbe.

Alhaji na so pe, iwa ebo sise ni iru asa be je, eyi ti o ro awon obi ibeta na lati mase

(Woju Ewe Keje)




new super active




Sachet 7k Junior 10k Medium 30k Large 55k Giant ₦1.75

# AWỌN ALAGA KANSUL TITUN

NI ọjọ Satide ti o kọja ti iṣe ọjọ kẹjọ oṣu kinni ọdun yi ni awọn Kansilọ Igbimọ Ijọba Ibilẹ mẹtala ni Ipinlẹ Ọyọ yan awọn alaga ati awọn alajumọṣiṣẹpọ wọn. Awọn alaga na niwọnyi:-

Kansul igboro Ibadan, Alhaji Ganiyu Kọlawọle Balogun. Awọn alabaṣiṣẹpọ rẹ ni Ọgbẹni Ọdẹtayọ Ọdẹtoyinbo fun eto ẹkọ, R. A. Asagidigbi fun eto ilera ati iṣẹ ode ati Alhaji J. K. Animaṣahun fun eto isuna.

Kansul Lagelu ni igberiko Ibadan ni a fi Ọgbẹni Samuel Ọlaṣọpe ṣe alaga rẹ. Awọn alabaṣiṣẹpọ rẹ ni: Alhaji Yusuf Wahabi fun eto ilera ati iṣẹ ode, Ọgbẹni Ọlatinwọ Ọtẹgbẹyẹ ni o si wa fun eto ẹkọ.

Ni Kansul Akinyẹle ni igberiko Ibadan kanna, Ọgbẹni Adebimpe Aderibigbe ni alaga. Awọn alajọṣiṣẹpọ rẹ ni Lere Ilọri fun eto ẹkọ, L. B. Ọlaniran ni o si nbojuto eto ilera ati iṣẹ ode.

Ni Kansul Iwo, Alhaji Ẹniọla Atanda ni alaga.

Ni Kansul Ejigbo, Ọgbẹni Adebisi Akinbelu ni alaga. Awọn alabaṣiṣẹpọ rẹ ni: Philip Oyeniyi ati Ọgbẹni Oyeyẹmi.

Ni Kansul Irepọdun Ọgbẹni Moses Adebayọ Akinṣola ni alaga Awọn alabaṣiṣẹpọ rẹ ni Fọlọrunṣọ Adediran fun eto ẹkọ ati Emmanuel Ọlanrewaju Ajayi fun eto ilera ati ode.

Ni Kansul Ileṣa, Alhaji Saliu Famuyide ni alaga. Awọn alabaṣiṣẹpọ rẹ ni M.A. Oṣungbohun fun eto ilera ati iṣẹ ode.

Ni Kansul Obokun, Ọrọ alaga koi yanju. Kansilọ Moses Adeleyẹ duro fun eto ilera ati iṣẹ ode; Kansilọ B. A. Adediran si wa fun eto ẹkọ ati Adele Alaga.

Ni Kansul Ọranmiyan, Ọgbẹni Oyeladun Oyewale ni alaga. Alhaji S. A. Balogun duro fun eto ilera ati iṣẹ ode, E. A. Adeagbo si duro fun eto ẹkọ.

Ni Kansul Ogbomọṣọ. Oloye Victor L. Lajide ni alaga. Amos Ajani duro fun eto ẹkọ ati J. B. Ọlaniyan fun eto ilera ati iṣẹ ode.

Ni Kansul Irẹpọdun, Ọgbẹni Ayọ Ọjẹwumi ni alaga. Suleiman Adegboye ni o wa fun eto ẹkọ ati Gbadebọ Akanni fun eto ilera ati iṣẹ ode.

Ni Kansul Ẹdẹ, Ọgbẹni L. O. Ọmọtọṣọ ni alaga. Alhaji S. A. Aderintọ ni o wa fun ilera ati iṣẹ ode, I. O. Ogunbunmi si wa fun eto ẹkọ.

Ni Kansul Oṣogbo, Ọgbẹni Goke Ajiboye ni alaga. Arabinrin Adisa Layiwọla ni o wa fun eto ilera ati iṣẹ ode, Alhaji Garuba Aṣiru si wa fun eto ẹkọ

Ni Kansul Ifẹlodun, Ọgagun Tunde Oyedele ni alaga.

Ni Kansul Ila, Ọmọ Ọba Isaac Adebayọ ni alaga

IPINLẸ OGUN

Ni Kansul Abẹokuta, Oloye Wahabi ailẹru ni alaga.

Ni Kansul Ẹgba Ọdẹda, Oloye G. L. Obe ni alaga.

Ni Kansul Ọbafẹmi Owode, Oloye E. O, Adeboye ni alaga.

Ni Kansul Ariwa Ẹgbado, N. Oyebọla Akinọla ni alaga

Ni Kansul Gusu Ẹgbado, Y. A. B. Ọlatunji ni alaga.

Ni Kansul Ijẹbu-Ode, Oloye Bisi Ọnabanjọ ni alaga.

Ni Kansul Ila-Oorun Ijẹbu, Adebọla Adekọya ni alaga.

Ni Kansul Ijẹbu—Rẹmọ; Ademọla Adesanya ni alaga.

ỌRỌ GOMINA

Ọrọ Gomina l'o ti ba awọn alaga ati Kansilọ Kansul abẹ wọn gbogbo sọrọ.

Adele Gomina Ipinlẹ Ogun, Ọgagun Aliyu Mohammed ti fọwọ si yiyan awọn alaga Kansul ti Ipinlẹ rẹ.

Ninu ọrọ ti o ba gbogbo alaga ati Kansilọ Ipinlẹ Ọyọ sọ ninu Ibadan ni ọjọ Ajé ọsẹ yi, Gomina na kilo fun wọn pe, ko gbọdọ si iwa ijẹkujẹ lọwọ wọn. O ni ẹnikẹni ninu wọn ko gbọdọ ba Kansul wọn da iṣẹ pọ paapaa iṣẹ Kọngilatọ ki nwọn ma baa f'ẹbọ jura.

Gomina na sọ pe a ko ko wọn jọ lati maa pero lori fifi ibikan ṣe ibujoko iṣẹ Kansul tabi lati maa yanju ọrọ aala ilẹ. O ni Kansulu yowu ti o ba kọja ilana Ijọba wọnyi, yio di tituka ni.



OLOYE VICTOR L. LAJIDE
Alaga Kansul Ogbomọṣọ

## Agbomojo

(Lati Oju Ewe Kẹfa)

anwo.

Inawo ọjọ na buaiya, rẹ ni awọn alabaṣẹyẹ ta awọn ọmọ na l'ọrẹ ọpọlọpọ.

Ara awọn enia ti o a sibẹ ni Alhaji Abul Salami Belo Bọlaji awọn maa nṣe ni keukewe Agba, Alhaji Abudul Wahabi Aderan Oluwakẹmi Akeuwe, Alhaji Imam ni iyegun, Alhaji Musifa Ailara, Alhaji Abul Karimu ti Oju Abẹ-.

Salami Atanda Alala, Isiaka Badiru, haja Jumeah Bọlaji, minatu Bọlaji, Alhaja adatu Ọlaniran.

Opọlọpọ enia ni o bẹrẹ si i fi ẹbun ranṣẹ awọn ibẹta na. Ara on ni, Alhaji Tiamiyu wal, Alhaji Oloye uritala Adams ti iṣe ọbaniyi Ogbomọṣọ.



ỌGAGUN DAVID JẸMIBẸWỌN
Gomina Ipinlẹ Ọyọ

## 'Saraa tori Olo'un'

(Lati Oju Ewe Kinni)
ko si gbọdọ gba saraa lowo ẹnikẹni nitori ohunkohun. Ko gbodo maa jo nitori saraa gbigba, ko gbodo korin, ko si gbodo patẹ ohunkohun nitori ati ri saraa gba.

Bakanna, ikede na so pe o tun lodi si ofin ki omode ti ko to iye odun ti a nwi yi maa fa alagbe kiri tabi ran an lowo ninu iṣẹ agbe ṣiṣe tabi ba iru ẹni bẹ gba saraa.

Ijoba tẹsiwaju pe, omo ti ko ba to iye odun ti a nwi na ko gbodo kiri oja laarin ilu. Ijoba so pe, ẹnikẹni ti o ba ru ofin na dagun Ijoba.

## Oga Olopa Meji

(Latl Oju Ewe Kinni)

Ni afikun, Agbejọro na so pe, nigbati Ọlop-miran ti o ju Ripẹto na de lẹhin ti oba na ti lo wakati diẹ ni atimole, ni o paṣẹ ki nwọn mu ọba na kuro ni itimole kiakia.

Nitorina, Oba na ninu ẹjo ti o pe, nro ile ẹjo giga na lati pasẹ pe ki awon Olopa na sanwo ti o joju fun oun gẹgẹ bi itanran pe nwon ti oun mole lai ba ofin mu.

Ninu idajo rẹ, Adajo ile ẹjo giga ilu Ilorin, Ọlola Anthony Ẹkundayo so pe, oun gba ẹri ti o wa niwaju ile ẹjo gbo pe, awon enia na ti Ọba na mole lai ba ofin mu.

Adajo na kilo gidigidi pe ile ẹjo oun ko nii gba ki a maa ti enia mole lai ba ofin mu: o si paṣẹ pe ki awon Ọlopa na lo san ẹẹdẹgbejo Naira (1,500:00) fun Ọba na gẹgẹ bi owo itanran, ki nwon si san ogorun Naira gẹgẹ bi owo irinsẹ.


# POOLS!

# 27 8 46
# 16 30 41

Two Way Nap



# OLORIRE O! OLORIRE O!

AWA ẸGBẸ ONIṢOWO ONIṢẸ ẸRỌ TI NJẸ

## WESTERN NIGERIAN TECHNICAL COMPANY LTD

NI A NKE SI NYIN
KI L'O ṢE Ọ-IWỌ OLUGBAṢE-ILE KIKỌ?
KI L'O ṢE Ọ-IWỌ KỌLEKỌLE?
KI L'O ṢE Ọ-IWỌ ONIṢOWO?
KI L'O ṢE O TI O ROJU KOKO?
TABI O KỌLE DIGBESE NI?
A! O MA ṢE O!!
KI L'O ṢE TI O KO RỌJU WAA RA
ẸRỌ WA YI:-



## Block Making Machine

### 9 x 9 x 18 with Spring N335·00

(EYI NI ẸRỌ TI NYỌ BULỌỌKU LORIṢIRIṢI IWỌN)
A NI 9 x 9 x 18 WITH SPRING FUN TITA

BI O BA TI NI ẸRỌ YI LỌWỌ
MA FOYA MỌ, IDẸRA TI DE FUN Ọ
OWO RẸ KO PỌ RARA N335.00 PERE NI
Bakanna ni a tun ni oriṣiriṣi ẹro ati ti ilota "BECO" fun tita pẹlu. Sa ma jafara, tara maa bo pẹlu Imolẹ Owuro kan ti a polowo ẹro yi si ninu lowo rẹ si:

## Western Nigerian Technical Company Limited

P.M. B. 5148: PHONE 22361/2
DUGBẸ ONIMATIRẸSI, IBADAN.

WENTEC 1955


Printed and published by the People's Star Press Limited, [illegible] Yemetu Aladorin P. M. B. [illegible], Ibadan. Olootu (Editor) Lawuyi Ogunniran, [illegible] Adekile Ibadan. Lagos Office: 16 [illegible] St. Phone [illegible]

THE EDITOR IMOLE OWURO
9/7/77
IBADAN.

IBADAN UNIVERSITY LIBRARY
11 JUL 1977
PUBLICATIONS ORDINANCE

WEEKS 50&51
Kongi WK 50
27 34 48
Wk 51
5 39 47
As ko BK W K 50
6 49 52 58
Wk 51
17 20 29 48
Ross Wk 50
7 & 37
WK 51
14&44

Imọlẹ Owurọ

EṢIN ỌRỌ WA: IMỌLẸ DE OKUNKUN PARADA!

SAMCO OF NIGERIA
WK 49
NAP 8 19 24
Perm 8 19 24 38 47
My Address ?
Not nessesary.
Always meet me in
Imole Owuro
Every Saturday

**9 21 46**

Independent Paper Vol X 1 O 805, SATURDAY JULY 9 — FRIDAY JULY 15 1977 (K OBO MEWA)

# EGUNGUN OLOOLU DA WARIWARI JO ỌMỌ ILE-IWE

EGUNGUN olokiki nni ti obinrin ki i ri ni ilu Ibadan, Egungun Oloolu, da wariwari jo awọn akẹkọ ati olukọ ile iwe Mọda kan ni adugbo Aperin nilu Ibadan ni owurọ ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi.

Ile iwe Mọda na ni nwọn npe ni ICC Modern Secondary Commercial School, Aperin Ibadan. Ọna ẹgbẹ Ṣọọṣi St Peter's, Aremọ ni mo gbọ pe Oloolu ati awọn kudẹẹfu rẹ ba wọ ile iwe na.

Gẹgẹ bi awọn enia ti ọrọ na ṣoju rẹ ti sọ fun mi, nwọn ni nṣe ni Oloolu dira ogun ti awọn kudẹẹfu rẹ si gbe ọpa oogun ati oniruuru oogun miran lọwọ bi ẹni ti nlọ si ogun.

Nwọn sọ fun mi pe, nigba ti Oloolu de ile iwe na, nṣe ni oun ati awọn ọmọlẹhin rẹ yawọ ọgba ile iwe na laibẹṣubẹgba, ti awọn janmaa ẹhin rẹ si da gbogbo eto ile iwe na lojuru.

### LATI ỌWỌ ONIROHIN WA

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn akẹkọ ile iwe na, ninu eyi ti ọdọmọbinrin pọju, bẹrẹ si i sa hilahilo kiri fun ẹmi won pẹlu awọn olukọ ti nwon jẹ obinrin pẹlu.

Mo gbọ pe, ọrọ na da yanpọnyanrin silẹ ni ọgba ile iwe ati adugbo na nitoripe are aṣubulebu ni awọn obinrin bẹrẹ si i sakiri.

Mo gbọ pe, ohun ti o fa a ti ọrọ Egungun yi fi ba awọn enia ati ọmọ ile iwe na lojiji ni pe, Egungun Oloolu ko gba ọna ibẹ kọja ri, eyi ko si jẹ ki nwọn ni ero tẹlẹ pe, Oloolu yio tọ wọn wa.

(Woju Ewe Kẹjọ)



EGUNGUN OLOOLU

## ORO OLOOTU

### Aseju Oloolu

EYI ni yio ṣe igbakẹta ti a kọ "Ọrọ Olootu" l'ori Egungun awọn ara Ibadan kan ti nwọn npe ni "Oloolu" ti ki i fi oju kan obinrin. Igba akọkọ waiye ni aiye Olubadan ijẹta, Alaiyeluwa Salawu Aminu. Ninu ọdun na ni awọn aladugbo da Oloolu l'ọna ni Isalẹ-Osi ati ni Yemẹtu Kanmbi nitori eyi ti Oloolu fi kọ ẹku rẹ silẹ nitori o sọ pe awọn aladugbo na ba oun ja.

OHUN ti o fa nkan wọnyi ba Oloolu nigbana ni pe, o jade gba ọjọ mẹrin gbako. Bi o tilẹ jẹ pe o ṣee ṣe ki Oloolu ati awọn onija ẹni agbaṣẹ ara wọn sinu tẹlẹ, ohun ti a ri kedere pe o mu abuku ba Oloolu nigbana ni pe, o kọja aaye rẹ nipa pe, ọjọ meji ni iṣẹdale gba a l'aye lati jade, ṣugbọn ọjọ mẹrin ni o fi jade ni ọdun ti a nwi yi.

NITORI ọrọ yi ni a fi kọ "Ọrọ Olootu" lati lodi si iwa ti Oloolu hu na, a si kesi Alaiyeluwa Salawu Aminu lati kilọ fun Egungun Oloolu lati so ewe agbejẹẹ mọwọ. A fi ye Kabiyesi nigbana pe, ara Ibadan l'o ni Oloolu, ki i ṣe Oloolu l'o ni Ibadan; nitorina, Oloolu ko l'etọ lati rekọja iṣẹdalẹ awọn enia Ibadan ti o ni in, bẹẹ ni ko lẹtọ lati da ilu Ibadan ti o ni in laamu tabi yi iṣẹdalẹ wọn pada tikararẹ. Nigbana ni a kesi Olubadan ti iṣe baba ara Ibadan ati ẹnikanṣoṣo ti o ni aṣẹ l'ori Egungun na lati kilọ fun un.

GẸGẸ bi a ti mọ iwa Oloogbe Ọba Salawu Aminu si, lẹsẹkẹsẹ ni oun ati Igbimọ rẹ forikori ti nwọn si ferokero. Nigbana ni Olubadan paṣẹ pe, Oloolu ko gbọdọ jade kọja ọjọ meji mọ, ki o si maa fi aisun ṣikẹta gẹgẹ bi iṣe rẹ lati lailai wa.

IGBA KẸTA ti a sọ "Ọrọ Olootu" l'ori Egungun Oloolu ni ti ọdun ti o kọja nigba ti Egun-

(Woju Ewe Kẹjọ)

**Apprentices Wanted**

LEARN to become a successful printer learn on modern machine with modern technique.

Parents, don't waste the time of your fresh Primary Six & Modern III School leavers; send them to learn modern printing, Machine operating and Book-binding from us. Apply personally today.

The Works Manager,
(Imọlẹ Owurọ)
N4/496B Yemẹtu Aladorin,
Ibadan:

# ÌSỌ̀RỌ̀-N'ÌGBÈSÌ...

## IPADE (63)

Adeyemọ Ojẹrinde
IREMOGUN! Mo tun de,
Ọmọ Ajiṣegiri;
Ara rẹ le tabi ko le
Ayinde Alayọ ọmọ baba Ladele.
Iyawo rẹ nkọ, ọmọ Ejigbọjọ
Ṣe tayatọmọ nbẹ l'alaafia ara?
Ẹẹ ya, ẹ ẹ ra, ẹ ẹ ni i tẹ.
Ṣe o ko gbagbe ọrọ ijọsi
L'ori ọrọ akoti wa?

Lawuyi Ogunniran
O ṣehun l'aiye, ọmọ Ajiṣegiri.
Iyawo mi nbẹ l'alaafia ara;
Gbogbo majẹṣin ni nbẹ l'alaafiia ara;
Iji Alugbe, baba Kafilatu.
Mo ti mura tan, ọmọ Ajiṣegiri;
Jẹ k'a maa ba faaji wa lọ.

Adeyemọ Ojẹrinde
Ayinde! Maa gbọ, ọmọ Ejigbọjọ,
Nigba ti o nsọrọ
Ninu ipade t'o kọja,
O sọ pe babalawo
A maa rubọ fun eṣu,
Atawo—atiṣegun ni i rubọ,
Ni aarin igboro;
Jọwọ, ọmọ Ejigbọjọ,
Taa ni *nwọn* nrubọ na si?

Lawuyi Ogunniran
Ohunkohun ti onikaluku ba fi ẹbọ sọri' ni
Ibi ti nwọn rubọ si.

Adeyẹmọ Ojẹrinde
Bawo ni nwọn se ngba ẹbọ na?

Lawuyi Oguneiran
Nigba ti elebọ ba gbe
Ẹbọ lọ si oju popo ni alẹ,
T'o ba d'ẹjọ keji
Ti ko ba nkankan ninu apaadi mọ,
A maa sọ pe, ẹbọ oun ru,
A ni, ẹbọ oun da,
A ni, awọn t'oun rubọ si.
Nwọn ti gba ẹbọ ọhun lọwọ oun.

Adeyẹmọ Ojẹrinde
O kare l'aiye Ayinde,
Mo ngb dun rẹ gidi,
Bi baba Alamu ti ngbadun Kosena.
Jọwọ ọmọ Ejigbọjọ,
Bawo ni oṣo tabi ajẹ,
Tabi emere
Tabi oloogun ika,
Tabi eṣu ọdara ṣe nko
Ẹbọ na kuro ninu awo
Ni oru ọganjọ
Bi gbogbo ilu ba sun?

Lawuyi Ogunniran
O kare l'aiye, ọmọ Ajiṣegiri,
Iru ohun ti o wi yi ti waiye ri
Nigba ti mo wa ni ewe
Ninu abule wa.
Ṣe ninu ile wa
Lati lailai wa,
Babalawo ko gboju
Ko mọ ifa ju iran mi lọ.
Nwọn mọ ifa a ṣe
Fun ẹni aiye ba nṣe,
Nwọn a maa ṣetutu,
Nwọn a si maa ṣe madarikan;
Nigba ti mo gbọnju
Ni mo ti nronu
Pe, taa ni i ko ẹbọ jẹ l'oju popo?
Anjọnnu ni tab'eniyan?
Nihin ni mo ti pinnu
Lati f'oju ri akẹbọjẹ
Ti i kẹbọjẹ ni oju gbangba
Nitorina ni alẹ ọjọ kan
Ti baba wa kan gbe ẹbọ lọ s'oju popo;
Mo rọra lọ sapamọ si kọrọ,
Mo nṣọ ẹbọ na ninu okunkun;
Titi gbogbo enia fi wọle sun,
Ng ko kuro ni kọrọ yẹn
Nibi ti mo ti nṣọ
Eni t'o maa kẹbọjẹ
Ajao! Ṣ'o ngbọ, baba Kafilatu?
Nigba ti o di aajin-dun
Ti ọwọ pa, ti ẹsẹ pa,
Nṣe ni mo ri aja nla kan
Ti o kọja wa sibi ẹbọ
Ti babalawo gbekalẹ l'oju ode!
Mo nwo aja fẹfẹ
Bi ẹni pe ki ng lẹ ẹ l'oko.
Ṣugbọn ero kan wa sọ si mi ninu
Pe, ki ng f'aja na silẹ ki ng woye;
Ni mo ba gbagbe oko
Ti mo fẹ lẹ tẹlẹ.
Koi pẹ ti mo jawọ ninu eyi
Ni mo ri aja na t'o bẹrẹ ti ẹbọ,
Ki ng to woran jinna,
Aja ti pari re dele!
Aja j'ekuru ọhun tan,
O tun jẹ eyin ti a ta epo si
T'o wa nibẹ gbogbo,
Aja jẹ gbogbo rẹ tan,
O tun la a delẹdelẹ,
Lẹyin eyi ni aja pẹhinda,
T'o ba faaji rẹ lọ!
Ajao! Ṣ'o ngbọ, ṣ'o nfiyesọrọ?
Aja jẹbọ tan, aja lọ;
Mo wa bẹrẹ si i ro o l'ọkan
Pe, aja ba ẹbọ ọhun jẹ
Nitoripe, aja ti fi ẹbọ j:
K'ẹni ti nwọn ru ẹbọ si
Too de ibi ẹbọ ni gbangba!
Mo wa bẹrẹ si i beere ọrọ l'ọkan:
Mo ni, bawo l'aja ṣe *l*ori laiya
T'o njẹ ẹbọ ti nwọn fi sọri
Oṣo ajẹ ati eṣu?
Mo ni, laiṣawawi,
Iku ni yio gbẹhin ẹranko
T'o ba ko ẹbọ ẹlẹbọ jẹ.
Ni kukuru, ero pe,
Aja ọhun fẹrẹ ku ni
Mo kuku nro l'ọkan.
Ajao! Ṣ'o ngbọ, ọmọ Ajiṣegiri.
Ṣe, a ki i bọ oriṣa l'oju ọfọnọn,
Nitori b'o ba di alẹ,
A maa tu pẹpẹ l'oju ọmọde,
A ki i si i sọrọ oribibẹ l'oju ọmọde,
Lọrunlọrun l'ọmọde e wo ni;
Gbogbo ọna bi ng o ṣe ṣofofo aja ọhun
Ni nbẹ l'ọkan nigbagbogbo
Ti mo ba f'oju kan baba ile wa.
Ọrọ pọ ninu ọrọ yi
Ọmọ Ajiṣegiri,
A ko le sọ ọ tan l'oni
Nitori, akoko nbuṣe.
B'o ba wa d'Ipade taa wa
A o maa ba faaji bọ.

Adeyẹmọ Ojẹrinde
Ayinde! O ṣe e ọmọ Ejigbọjọ,
Ori rẹ pe, mo si gbadun rẹ.

(Woju Ewe Kẹfa)


Jaloke Nap

9
11
60

IWE IGBAẸLODE
DARA PUPỌ.
RA TIRẸ NIBẸ
1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agba 20k
2. Kurani ọgọta esu ni ede Yoruba ₦10 Esu kan (50k)
3. Yasin ni Yoruba ati Isawaka 50k
4. Zabura ati Itumọ (₦1)
5. Zabura Yoruba (₦1)
6. Iwe Aiye Akamara (₦1)
7. Iwe Eniaṣoro (₦1) Adedẹwẹ (50k)
8. Iwosan Ajẹbidan Ogun enia dudu (₦6); Kekere (50k)
9. Iwe ala ni nla (₦2)
10. Kekere (50k)
11. Iwe Oogun iwosan (₦2.50) Kekere (75k)
12. Itan Anabi ati Yisa (₦1)
13. English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (50k)

FI OWO ATI STAMP (5k) RANṢẸ SI

(1) Alufa Yisa Igbaẹlode N2/394a Odoye Adeọyọ Rd, P. O. Box 3365, Mapo Ibadan.



(2) Alufa Igbaẹlode, Mọṣalaṣi Idi Iṣin St, Isa'ọ Koto P. O Box 17 Ilọrin.



WOLI S. I. OWOẸYẸ
Oniwaasu Naa.

# Akéde ọna Iyè

ONAKANṢOṢO SI IYE AINIPẸKUN

BIBELI MIMỌ

# Eese ti iwo fi nsaniyan asan?

"TAANI ninu nyin nipa aniyan ṣiṣe ti o le fi igbọnwọ kan kun ọjọ aiye rẹ?" Matteu 6; 27.

Mo ki nyin, ẹnyin ọmọ enia pe, ẹ ku ọjọ mẹta.

Jesu Kristi tun ji ninu agbara Rẹ l'oni lati ba ọ sọrọ; nitorina, farabalẹ gbọ ọrọ Rẹ.

Ohun na ti Jesu Kristi nbeere lọwọ rẹ l'oni ni pe, "Taani o le fi igbọnwọ kan ku ọjọ aiye rẹ?"

Iwọ ti o kun fun aniyan aiye yi ti o ko si fi Ọlọrun ṣe igbẹkẹle re ni Jesu Kristi nba wi. Njẹ nigba ti o kun fun aniyan pe, iwọ yio da igba, iwọ yio da awo, eeṣe ti iwọ fi nsọrọ ti o si nṣe ileri bi ẹni pe iwọ ni o ni ẹmi ara rẹ? Iwọ ha le fi igbọnwọ kan kun ọjọ aiye rẹ bi?

L'ode oni, ohun ti ọmọ araiye nkanju lati ni ni owo lai beere iru ohun ti owo bẹẹ le mu wa bi nwọn ba tilẹ ni in.

Gbogbo iwa bii faiyawọ, ọwọngogo ọja, ififajale, jibiti lilu ti awọn enia orilẹ-ede wa sọ di iṣẹ wọn l'oni, jẹ eyi ti awọn enia ti o sa fẹ fi dandan ni owo dasilẹ. Awọn wọnyi l'o fi ipa aniyan aiye ti nwọn nlepa ko ọpọ iṣoro ba ilẹ wa.

Nigba ti ọpọ ba fi iru ọna aitọ bayi ko ọrọ jọ tan, a bẹrẹ si inawo na ni inakuna. Tabi, kini ero ẹni ti ndaṣọ alapomẹrin Naira si ọrun lẹẹkanṣoṣo? Iwọ onigberaga enia, njẹ iwọ ha wọ aṣọ ti inu iya rẹ jade wa bi? Eyi ti a ba si fi sinku rẹ ha le ṣee jogun fun ọmọ rẹ bi; tabi ki haa ṣe inu iboji ni yio ra si?

Nitori ohun ifẹkufẹ ati asan aiye yi ni ọmọ araiye fi nfi ọna aitọ ko ọrọ jọ kiri. Nwọn nṣe aniyan lai fi ohun gbogbo le Ọlọrun lọwọ. Idi niyi ti Bibeli fi beere ninu iwe Matteu Ori 6 ẹsẹ 28 pe, "Eeṣe ti ẹnyin si fi nṣe aniyan nitori aṣọ?"

Ọpọ enia l'o ti di ero ọrun apadi nitori aniyan aiye yi; ọpọ ni orukọ rẹ ti bajẹ, ọpọ l'o si ti di ẹni itanu niwaju Olodumare.

Ẹ jẹ ki o ye nyin pe, ẹnikẹni ti o ba nlepa aniyan aiye yi ki iṣe ti Ọlọrun bikoṣe ti eṣu, awọn na si ni keferi. Ko si ibi ti nwọn ko si ni aiye yi. Bi nwọn ni ẹbun orin, nwọn ko ni i fi yin Oluwa. Kaka bẹẹ, ọna ti nwọn yio gba maa fi yin eṣu, ki nwọn baa le ri owo kojọ lojiji ni nwọn yio maa ba kiri.

Bi nwọn ba kọṣẹ agẹrun tan, ṣugbọn ti nwọn tun gbọ pe, iṣẹ Mẹkanniiki ta, nwọn a sare pa iṣẹ agẹrun ti, nwọn a gba ibi iṣẹ Mẹkaniiki lọ.

Bi nwọn ba de ibi iṣẹ Mẹkaniiki tan ti nwọn tun gbọ pe awọn kan ri ṣe nibi faiyawọ, nwọn a tun gba ọna oko faiyawọ lọ.

Bayi ni ọmọ aiye yi ko aniyan aiye lekan; ti nwọn nlepa aniyan aiye ka tobẹẹ ti nwọn fi gbagbe Ọlọrun Ẹlẹda wọn ti O ni ẹmi wọn, ti O si le beere ẹmi na lọwọ wọn lẹsẹkẹsẹ.

Ọlọrun ni O da wa, Oun kanna ni O si le din ọjọ aiye ẹda ku, ti O si le fi kun un bi o ba fẹ. Nitorina iwọ ọmọ enia, Ọrọ Ọlọrun nbeere l'ọwọ rẹ l'oni pe, ninu gbogbo irinajo rẹ kaakiri, yala sile alawo tabi sile abokusọrọ tabi sile alalupayida, nibo ni a ti fun ọ ni idaniloju pe, a o fi kun ọjọ aiye rẹ?

Ọmọ enia, niwọn igba ti iwọ ko le fi kun ọjọ aiye rẹ, eeṣe ti iwọ ko kuku duro de Oluwa ki o ye maa lepa aniyan aiye ka? Bi iwọ ba gbẹkẹ rẹ le Oluwa ti iwọ si nrin ni ọna Rẹ, Oluwa ko jẹ gbagbe rẹ.

Bi a ba beere lọwọ ẹlomiran t'o kọle, t'o ra mọto tan ti o tun wa ntori owo ṣe ipalara fun ọmọ ẹlomiran kiri ki o ba le di ọlọrọ pataki, ohun ti yio sọ ni pe, ohun npese silẹ de atirandiran ọmọ oun ni.

A! iwọ ọmọ enia, iwọ nṣe aniyan nitori ọla! Njẹ ẹnikẹni l'aiye yi ha le tẹba silẹ de oyun ti nwọn ko ti i bi?

Ṣugbọn Jesu Kristi ti fi owe sọ ohun ti a le fi iru ẹni bẹẹ we. Oluwa rẹ na ni: "Ilẹ ọkunrin kan ọlọrọ so eso ọpọlọpọ, o si ro ninu ara rẹ wi pe, emi o ti ṣe nitori ti emi ko ni ibi ti ng o gbe ko eso ati ọrọ mi si. O wi pe, emi o wo aka mi palẹ ng o si kọ eyi ti o tobi, nibẹ ni ng o to eso ati ọrọ mi jọ si, emi o wi fun ọkan mi pe, Iwọ li ọrọ pupọ ti a tojọ fun ọpọ ọdun; sinmi, maa jẹ, maa mu, maa yọ. Ṣugbọn Ọlọrun wi fun un pe, Iwọ aṣiwere, li oni yi li a o bere ẹmi rẹ lọwọ rẹ. Njẹ titaa ni nkan wọnni yio ha ṣe ti iwọ ti pese silẹ? Bẹẹ ni ẹni ti o to iṣura jọ fun ara rẹ ti ko si li ọrọ l'ọdọ Ọlọrun": Luku 12; 16-21.

Iwọ ọmọ enia, o nsare lepa aniyan aiye yi kiri. Njẹ, kini ere aniyan rẹ lai si imọ Ọlọrun? Iwọ ko ha mọ pe, ọrọ inu aiye yi nbọ wa di ofo ni?

Nitorina, ṣọra pẹlu lilepa aniyan aiye yi. Maṣe gbe ẹmi rẹ le ohun asan aiye yi nitoripe, ofo ni. Maa gbẹkẹle Oluwa Ọlọrun rẹ ki o si maa pa ofin rẹ mọ, Oun ni yio si maa pese fun aini rẹ.

ADURA

Oluwa, fa mi kuro ninu aniyan ohun asan aiye ki ng le ni itẹlọrun ninu ibukun Rẹ ti i mu ni la lai si laalaa, Aamin.

**Lati Owo Woli S. I. Owoeye**


**Nigeria New States Co.**

Jẹ atẹwe asiko. Bi oba fẹ tẹ oniruuru iwe Kalẹnda, Almanak ati bẹẹbẹẹ lo, Ile Iṣẹ wa wa ni:

18, Ọdunlami Street,
Phone 27017, Lagos.



## IWE ỌRỌ ỌLỌRUN

Fun anfani ẹnyin ti o ṣoro fun lati ri iwe mi yi ra ni ọkookan, mo ti seto lati maa fi apapọ iwe na ṣọwọ si nyin ni aadọta Kọbọ (50k) pere.

1. ADURA AIYERAIYE
2. IBANIWI OLUWA
3. KINI ILE AIYE ṢE BAJẸ?
4. Ẹ JOWO ARA NYIN FUN OLUWA

Bi o ba ti fi Postal Order 50k ṣọwọ si mi, ng o fi apapọ iwe na ṣọwọ si ọ lagbara Oluwa. Fi owo ranṣẹ si:

Woli S. I. Owoẹyẹ
Box 1206,
Ibadan.

# Ẹgbọ t'emi

## O dara bee

OLOOTU,

LAIPẸ yi ni mo ka aba kan ninu Imọlẹ Owurọ, eyi ti Ọgbẹni Ajani Iyowuawi lati Abẹokuta da pe, ki Ijoba maa ju ẹni ti o ba wa moto pa enia nipa are asaju ati aitẹle ofin irinna, tabi nipa oti amuyo ati taba igbo mimu, ki a maa ju iru ẹni bẹẹ si ẹwon ọdun mẹẹdogbon, ki iru ẹni bẹẹ ma si ṣe wa moto mo lailai.

Aba Ajani Iyowuawi na dara pupo, o si yẹ ki Ijoba Ologun gbaa wole.

Emi ni,
Tiamiyu Ẹlẹro-ogi,
Tede.

## E ba ni f'ofin de agbero

OLOOTU,

GBA mi l'aye lati kesi Ijọba Ologun Apapo lati ba ni fi ofin ologun de iṣẹ agbero ṣiṣe jakejado ilẹ Naijiria nitoripe ayonilẹnu ni won, nwon si le da rogbodiyan silẹ laarin ilu nipa iwa won.

Paapaa, mo kesi Gomina wa ni Ipinlẹ Ọyọ nihin, Ọgagun David Jẹmibẹwon lati ba wa pa ẹsẹ awon agbero run ni ilu Ibadan nitoripe iyọnu wọn pọju.

Ọpọ ole ni nfi juujuu ju awọn enia l'oju ti nwọn fi nja ero lole ni awọn budo ọkọ wa gbogbo.

Mo tilẹ nbere, kini agbero wulo fun nibi moto wiwọ? Ẹni ti o nlọ si irinajo ti mọ ilu ti oun nlọ ati ibi ti oun yio ti wọkọ. Bawo ni ọrọ ṣe di ohun ti a o maa wa agbero ka ki a to le wọ mọto?

Awọn agbero lo njẹ ki ole pọju ni awọn budo ọkọ wa gbogbo, awọn l'o njẹ ki owo ọkọ wiwọ ga si i, awọn ni nwọn nda rogbodiyan silẹ ni awọn budo ọkọ wa gbogbo.

Nitorina mo kesi Ijọba ologun Apapọ lati fi ofin pa agbero rẹ.

Emi ni
David Ogundare,
Ibadan.

## E gba wa l'ori oro fulawa

OLOOTU,

ỌRỌ owon fulawa yi ti wa di ohun ti ko ṣee faramo mo ni ilẹ wa.

Nigba ti a nra apo fulawa ni Naira mejila ati ogun kobo, a nkigbe pe o won pupo.

Ṣugbon bayi, o ti fofẹrẹ si Naira mẹtalelogun (₦23.00)

Nibo wa ni oko Naijiria ngbe wa lọ yi o? Njẹ burẹdi jijẹ ko ni i di ohun ti olowo nikan le jẹ l'ojo iwaju?

Gbogbo aiye ni o mo pe, burẹdi jẹ ounjẹ talaka. Gbogbo nkan wongogo, fulawa na tun won!

Mo fi iwe yi ke si Ijoba ki nwon jowo ba wa gbogunti adanwo ti fulawa yi nitoripe nkan ko gbodo maa ri bayi lo. Ẹ ma jẹ ki iyan wole to wa.

Emi ni,
S. L. Maranro,
Ibadan.

**2 9 60**

**11 23 44 54**

# Anfani ti Imole Owuro nse

OLOOTU,

MO fẹran iwe Imolẹ Owuro yi pupo nitori awon anfani ti mo nri gba nipa kika iwe na.

Ni ona kinni, irohin akonilogbon ti enia fi le ṣora ninu aiye kun inu rẹ denu.

Eyi ti o buyaari ju ninu anfani na ni ti iwaasu Woli S. I. Owoẹyẹ, eyi ti o nmu mi tẹsiwaju ninu Ọro Ọlorun, ti o si nso mi ji kiakia. Mo nka Bibeli mi lojoojumo lati tun igbesi aiye mi ṣe.

Oruko iwe nyin paapaa wu mi bẹ ni oruko egbẹ nyin "Ẹgbẹ Imolẹ Owuro" si dara pupo. Bibeli Ọro Ọlorun tun jẹri si i ninu Gẹnẹsisi 1:3 pe: "Ọlorun si wi pe, ki Imolẹ ki o wa molẹ si wa."

Ẹsẹ kẹrin so pe, "Ọlorun si ri Imolẹ na pe, o dara: Ọlorun si paala si agbedemeji okunkun oun Imolẹ". Ẹsẹ karun so pe, "Ọlorun si pe Imolẹ ni osan ati okunkun ni Oru."

Ninu iwe Matthew ori 5:16, a ka a re, "Ẹ jẹ ki Imolẹ nyin ki o molẹ tobẹẹ niwaju enia ki nwon ki o le maa ri iṣẹ rere nyin, ki a si le maa yin Baba nyin ti nbẹ li Ọrun l'ogo".

Olootu, adura mi ni pe, ki Oluwa maṣai tan Imolẹ Rẹ si okunkun wa ninu aiye wa, Aamin.

Emi ni,
Raphael O Ọlanrewaju,
Eko



# Aiyedetisola Commercial Electrical Store:

**Will satisfy all your electronics needs at reasonable prices**

**Call at**

**N27&41 I.C.C STALL
AGODI GATE
IBADAN**

# Nwon gba iso mo Baale ile lori

IROHIN lati Ajegunlẹ Apapa ni ilu Eko fi ye wa pe, kayeefi ni o jẹ fun awon mehaaya inu ile kan ni adugbo na nigba ti nwon jijade ni owuro kutukutu ti nwon ba oku baale na ni gbangba ode ile na ninu agbara ejẹ.

Gẹgẹ bi irohin ti wi, nwon ni okan ninu awon mehaaya ti o ko jijade ni o ri oku baale won na giika nile, ni o ba sare wole pe ki awon ara ile wa wo enmo l'oju ode.

Irohin so pe kayeefi ni o jẹ fun awon aladugbo ati awon ara ile na nigba ti nwon ri i pe nwon gba iṣo insi mẹfa mo agbari baale won oloogbe na.

# Ajala jade l'aiye

NWỌN ti kede iku okan ninu ipilẹ omo Ijo Saint James' Church ni ilu Ilie, Alagba Samuel Woye Ajala, ẹni ti o fi ilẹ bora bi aṣo lẹhin ti o ti lo ogorin odun l'aiye gẹgẹ bi nwon ti wi.

Oloogbe na nigba aiye rẹ, ni babasalẹ ẹgbẹ Cooperative Produce Marketing Society Limited ni ilu Ilie l'ẹba Ọṣogbo.

Ọpo omo ati omo-omo l'o gbẹhin rẹ. Ara won ni Kansilo M. O. Ajala ti Kansul Oṣogbo, M. I. Ajala, John Ayo Ajala, Oyeleke Ajala, Julianah Ajala, Emily Ajala, Taiye ati Kẹhinde Ajala, Bode Ajala ati Idowu Belo.

Ọpolopo enia nlanla ati mẹkunnu ni o pejupesẹ nibi isinku oloogbe na.

11 & 12

# Omo Ojokan poora ni ile iwosan

AWỌN Ọlopa Mina ni Ipinlẹ Niger ti gbe irohin kan jade pe, nwon ti ji omo ojo kan gbe ni ile iwosan Ijoba ni ilu Bida.

Irohin awon Ọlopa na ṣalaye pe, lẹhin ti obinrin kan ti o pe ara rẹ ni ibatan abiyamo na wo ni omo titun na di awati.

Awon Ọlopa so pe ko pẹ ti iya omo na, Iyaalin Fatima Muhamed, ara abuleko Edogoki ni agbegbe Bida bimo tan ti omo na poora. Nwon ni nibi ti oju iya omo na ti ṣẹṣẹ nwale lẹhin irora ibimo, ni gbomogbomo na gbe omo na lo.

Awon Ọlopa so pe, awon gbo pe Tapi ni obinrin ti o ji omo na gbe, o loyun sinu, o si wo aṣo kan ti nwon ya Naira aladipo marun si l'ara.

Siwaju si i, awon Ọlopa so pe, ni ojo kerindinlogun oṣu kẹfa odun yi ni iṣẹlẹ na ṣẹlẹ ni ile iwosan Ijoba ni Bida.

Awon Ọlopa wa kesi gbogbo enia pe ki ẹnikẹni ti o ba le ṣe iranlowo ti awon yio fi ri obinrin na gbamu, ki oluwarẹ tete wa fi to awon Ọlopa Ọtẹlẹmuyẹ leti ni ilu Mina.

6 21 32

# Ara Kansul Akinyele bori Elero - ogi

IROHIN ti o tẹ wa lowo lati ilu Moniya ti iṣe olu ile iṣẹ Kansul Akinyẹle niha Ariwa ile Ibadan, fi ye wa pe awon ẹlẹro ogi agbegbe na ti ju awa silẹ

Awon ẹlẹro na ni a gbo pe o ṣe eyi lẹhin aṣẹ ti awon enia agbegbe ibẹ pa pe, ẹnikẹni ko gbodo gbe ohunkohun lo si odo awon ẹlẹro ogi mo ni agbegbe na titi ti awon ẹlẹro na yio fi ju awa silẹ.

Awon ẹlẹro na ni o kede laipẹ yi pe, Kobo mẹwa ni awon yio maa gba dipo Kobo marun ti nwon ngba l'ori abọ agbado tabi abo erce kan, ṣugbon ti awon enia Agbegbe na taku pe, awon ko le faramo on.

Ninu ipade ẹlẹẹkeji ti o waiye ni ilu Moniya laipẹ yi labẹ akoso oga ile iṣẹ Kansul na, ni awon ẹgbẹ ẹlẹro ogi na ti kede pe, awon ko fi kun owo ẹro lilo na mo.

Onirohin wa so pe bayi, awon enia agbegbe na ti tun bẹrẹ si i maa lo nkan lodo awon ẹlẹro ogi ni adugbo olukuluku won.

## Isoro n' igbesi

(Lati Oju Ewe Kẹta)

B'Ọlọrun fẹ, oo ni i ṣiṣe,
O o ni i gbogbo oju,
O o ni i tanna arun kalẹ;
Ọpọlọ rẹ ko ni i daru;
Gbogbo ọmọ t'o mọ ọ ni baba
Ko ni i bọsọnu lọwọ rẹ.
Agbara lọwọ Ọlọruu Ọga Ogo
T'O da gbogbo wa.

KEREO
GBOGBO - ENIA!
fun
•Ipolowo ọja ati Ikede,
•Akiyesi ati Itufọ,
•Iranti oku ati Ikede Ariya,
•Ikilọ ati bẹbẹ lọ;
•Tabi Almanak ati Kalẹnda tite.
DARAPỌ PẸLU AWỌN ỌLỌGBỌN ENIA TI O NṢEE SI INU (IMỌLẸ OWURỌ) TI O GBAJUMỌ KARI AIYE. OWO TI A NGBA KOPỌ, SA KỌWE TABI KI O WA RI :-
Advertisement Manager:
IMỌLẸ OWURỌ
N4/4968 YEMETU ALADORIN.
P.M.B. 5230, IBADAN.




# Ayisatu Ologun gbe awo are ijala jade


AYISATU OLOGUN
Onijala Atata

LOJU ewe kinni iwe Imọlẹ Owurọ ti ọsẹ t'o koja lọhun ni ẹ ti ri ipolowo ọja rẹkọọdu titun ti Olokiki Obinrin ninu are Ọdẹ (Ijala Ogun) nni Ayisatu Ologun ati ẹgbẹ alare ijala rẹ ṣẹṣẹ ṣe jade fun gbogbo Olufẹ are Ode kaakiri ilẹ Naijiria.

Ayisatu Ologun jẹ iiumọka nibi are ijala o si fẹrẹ jẹ pe, ko si ilu Yoruba kan ti nwọn ko ti mọ ọn.. Bakanna ni awọn enia maa ngbadun rẹ lori Redio.

Mo ranti ara awọn gbolohun ti o maa nsaba fi kọrin nigbana eyi ti o jẹ pe gbolohun na ni awọn enia fi maa ndapara bayi pe, "Ti a ba ni ɔ to, Onilu a si sinmi, Onikannago o ṣe suuru" ati "Ajikẹ Ogun nrele wọn, Ọba ma fi oni ya wa Ayisatu o, Ajikẹ Ogun nrele wọn" eyi ti tọmọdetagba fi maa nṣe orin kọ nigbana titi di oni.

Ninu rẹkọọdu rẹ titun yi, nwọn bẹrẹ ilu Ode ti o fakiki; lẹhin eyi ni Ayisatu wa ki ohun Ijala bọ ẹmu nibiti o ti juba fun gbogbo Odẹ ti o wa ni Ipinlẹ Ọyọ, Ogun, Ondo ati Kwara, ti o si nki ipọnri awọn Ọdẹ na ni mẹsan-mẹwa.

Bi o ti mu ẹnu kuro nibi yi ni o wa ki Oloogbe Adeoye Afin-Oro ati Ọba Oloro ti Ẹkun — mẹsan — Oro pẹlu oriki orilẹ Oro. Bakanna ni o lọ si ilu Ileṣa nibi ti o si ki ipọnri Ijẹṣa ati Ọlayiwọla Fadahunsi. O sọ itan diẹ nipa Ogendengbe Agbogungboro, akọni Ijẹṣa.


ALHAJI AMỌDU ỌDẸ
Ẹni ti o tẹ awo na.

Odi keji awo yi ni o si ki Iku Baba Yeye, Ọba Lamidi Adeyẹmi, Alaafin Ọyọ. O ki Alaafin Ọyọ ti o fi jẹ pe, ẹni ti ki iṣe ọmọ Ọba paapaa ti o ba gbọ ọ, ori rẹ yio maa wu ni.

Gbogbo bi o ti nsun ijala yi, bẹẹ ni awọn onilu rẹ nda ilu pọ lẹẹkọọkan pẹlu egbe orin ti o dun jo.

Awo Ayisatu Ologun yi, eyi ti nọnba rẹ jẹ AAOLP 002 panbambari, koṣeemani ni fun gbogbo ojulowo Ọmọ Kaarọ – Oojiire nitori ijinlẹ ede Yoruba ati Oriki awọn idile ti o ki sibẹ; paapaa awọn Yoruba ti nwọn wa ni Ipinlẹ Kwara, ni o ki ju sinu awo na.

Ile–Iṣẹ Alhaji Amọdu Ọdẹ Sound Studio ni o gbe awo na jade.

Ẹnikẹni ti o ba ra awo na ko fi owo jona, ohun rere, amunudun ni o fi owo ra. Ko si ẹni ti yio gbọ awo na ti ko nii ra a lọ silẹ. O le ri awo na jakejado ile itaja rẹkọọdu l'adugbo rẹ tabi ki ẹ kuku beere l'ọdọ.

Alhaji Amọdu – Ọdẹ,
62, Nnamdi Azikiwe St,
Lagos Tel. 27447.

1 19 20 54 58 60

# 'Nwon lu Alhaji ni alupa'

AWỌN Ọlọpa ilu Kano ti fa awọn enia mẹrin kan wa sile ẹjọ Magistrate kan n'ilu na lati koju ẹjọ ẹsun pe nwọn lu ọkunrin Alhaji kan ni alupa.

Awọn ọdaran mẹrẹẹrin ni okunrin kan ati obinrin mẹta. Awọn ni: Muhamed Hurse ti iṣe ọmọ ọdun mejidinlogun Awọn obinrin meta na ni: Gamboya Abudulahi ti iṣe ọmọ ogun ọdun, Esther Hassan ti iṣe ọmọ ọdun mejilelogun ati Kafari Mohamed ti ṣe ọmọ ọdun mejilelogun.

Awọn afẹsunkanni sọ pe ni ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu karun ọdun yi ni awọn ọdaran na pa Alhaji Abass l'ara tobẹẹ ti o fi gba ibi ipalara na di ero ọrun nigba ti nwọn gbe e de ile iwosan.

Nitorina, awọn afẹsunkanni fi ye ile ẹjọ na pe, awọn enia na ti daran ẹjọ ipania, nwọn si nfẹ ki ile ẹjọ da wọn lẹbi pe, awọn ni nwọn pa Alhaji Abasss Ali.

Ṣugbọn Agbẹjọro awọn ọdaran na rọ ile ẹjọ lati gba iduro awọn ẹlẹjọ rẹ.

Ṣugbọn awọn afẹsunkanni tako ẹbẹ na. Nwọn rọ Adajọ lati ma ṣe gba iduro awọn ọdaran na "nitori pe nwọn ki i ṣe ọmọ ilẹ Naijiria nwọn si le na papa bora bi ile ẹjọ ba gba iduro wọn".

Adajọ ile ẹjọ na ko lati gba iduro awọn ọdaran na, o si paṣẹ ki nwọn lọ fi wọn pamọ si ọgba ẹwọn.

11 JUL 1977

# ORO OLOOTU

(Lati Oju Ewe Kinni)

gun na ati Alhaji Ajagbemokeferi digbolu ara wọn. A tọka si ofin ti o fi ẹtọ olukuluku ọmọ Naijiria mule lati sin ẹsin ti o ba wu u lai gbọdọ si ṣyolẹnu fun un; a si lodi si iwa ati iṣe ti o le da alaafia ilu ru nigbana.

ṢUGBỌN bi a ba ka irohin oju ewe kinni ninu iwe wa yi, a sọ bi Egungun Oloolu ṣe rati wọ ọgba ile iwe I C C Modern Secondary Commercial School, Aperin, Ibadan ti rudurudu si wọ ile iwe na, ati ayika rẹ, ati bi o ṣe jẹ pe, igba ti owo bọsowọ Oloolu ni Oloolu to fi ọgba ile iwe na silẹ! Ile iwe wa di ibi ti ko ni ọwọ mọ! Nigbawo ni ile iwosan, ile isin Onigbagbọ ati ti Musulumi ko le di ibi ẹgan lọwọ Oloolu? Bi o ba da bẹẹ, taa l'o le mọ iru ọmọ t'o le bi?

AWA gẹgẹ bi iwe irohin ki i mu omulomu, a ki i fi ẹtẹ silẹ ki a maa pa lapalapa, a ki i ri iwa ti ko dara nilẹ ki a maa fọwọ bo o, a ki i dajọ eke, a ki i ṣegbe lẹhin aisunwọn; ko si si bi otitọ ṣe le koro to ki a ma sọ o, bibẹẹkọ, a jẹ pe, a ko ṣiṣẹ wa lotitọ ati lododo ni.

NITORINA, aṣeju ni Egungun Oloolu ṣe l'ori jijawọnu ọgba ile iwe Mọda Aperin. A ha le tori pe, Oloolu fẹ jade ki gbogbo ile iwe, ile iwosan, ile igbẹbi, ọja ita—ounjẹ, ile iṣowo ati ile nlanla di titipa bi? Ninu Oloolu ati ara ilu, taa ni Ọga ara wọn? Ohun ti Oloolu ba nfẹ l'o ṣe pataki ni tabi ohun ti ara Ibadan ba nfẹ? Ominira Oloolu l'o ṣe pataki ni tabi ominira gbogbo olugbe Ibadan?

NITORINA, bi o tilẹ jẹ pe Oloolu lẹtọ gẹgẹ bi aṣa wa ati gẹgẹ bi ofin iṣelu ilẹ wa lati jade, ohun ti o ṣe pataki julọ ni lati ṣayẹwo iru anfani ti jijade rẹ nṣe ilu. L'ode oni, obinrin nṣiṣẹ ilu kaakiri. Nwọn nnaja, nwọn nṣe nọọsi, nwọn nṣe Tiṣa ati bẹẹbẹẹ lọ, ko si da bii ti atijọ ti obinrin nṣiṣẹ ile nikan. Bi aiye ba si nyi, nṣe l'o yẹ ki a maa ba aiye yi.

IMỌRAN wa ni pe, ki Olubadan ati awọn Ijoye rẹ forikori, ki nwọn sọ fun Oloolu pe ko gbọdọ ya ọgba ile iwe mọ, ko gbọdọ ya Ṣọọṣi, Mọṣalaaṣi, Ile iwosan tabi de ọja nibikibi, bẹẹ ni bi yio ba jade l'ọdun, agogo mẹjọ alẹ ni ko maa bẹrẹ aisun, ko si gbọdọ jade kọja ọjọ meji. Bi o ba jade ni agogo mẹsan owurọ ti onisẹ yio ti lọ sibi iṣẹ tan, ki o wọle pada ni agogo mẹta irọlẹ. Aṣa ibilẹ ni a nṣe ki i ṣe owo ṣiṣe; awọn Ijoye ni a sọ pe a nlọ ki ku ọdun, ki i ṣe ki a maa kiri oju/e gbogbo nitori ati ri owo ati ẹbun gba lọwọ ẹnikẹni ti o ba sa ti lowo lọwọ.

NI kukuru, o ti di dandan bi a ko ba fẹ ki eto ọrọ aje ilu fasẹhin, ti a ko ba fẹ ki aṣa ibilẹ wa di ohun ti awọn ara ilu yio maa ba awo rẹ jẹ, ti a ko si fẹ ki aṣa wa di ohun ti fi nhalẹ mọ awọn obinrin wa ṣugbọn ti a nlọ fi han awọn obinrin ajeji ti o lowo lọwọ, ki a kuku joko ronu, iru ọna ti fi le ṣe ayipada rẹ. Bi o ba ṣe e ṣe, ki jijade Oloolu kuku bọ si agogo mẹjọ alẹ si agogo mẹfa owurọ gẹgẹ bi awọn Oloro ti nṣe ni Iṣẹyin. O pẹ ni, o ya ni, eyi ni yio gbẹhin ọrọ na. A kesi Olubadan lati fi aṣeju Egungun Oloolu han an nitoripe, aṣeju rẹ npọ.

Ẹẹmẹrin l'o tun jade l'odun yi.

Ṣe eyi dara bẹẹ?

## Egungun Oloolu

(Lati oju ewe kejo)

Ni akoko ti Oloolu ati awọn ero ẹhin rẹ yawọ ọgba ile iwe na, nṣe ni ipaiya ba gbogbo ile iwe alakọbẹrẹ ati ile iwe Girama ti o wa ni ayika ibẹ, ti olukuluku ọmọde, paapaa awọn aṣẹsẹbẹrẹ ile iwe si nsa kijokijo kiri bi ọmọ ti o sọnu lẹhin iya rẹ.

Gẹgẹ bi mọ ti gbọ, a fi igba ti Oloolu gba owo lọwọ awọn olukọ ile ẹkọ Mọda ti a wi yi ni o to fi ile iwe na silẹ.

Agbọrọsọ kan ninu ile iwe na ti ko fẹ ki aiye mo oruko oun, so fun mi pe, eyi ni igba akoko ti Egungun yio yawo ogba ile iwe kaa nilu Ibadan lati ijo ti ile iwe ti bẹrẹ ni ilu na lati nkan bi odun 1852. O ni nipa ohun ti Oloolu ṣe yi, o fi han pe, ẹnikẹni ko bowo fun ile iwe mo.


# OLORIRE O! OLORIRE O!

AWA ẸGBẸ ONIṢOWO ONIṢẸ ẸRỌ TI NJẸ

## WESTERN NIGERIAN TECHNICAL COMPANY LTD

TI GBE ẸRỌ ALAGBARA-NLA KAN DE!
IWỌ AGBẸ TI NWA OWO,
O KO MỌ PE,
"OWO L'A FII PEENA OWO?"
KINI ṢE TI O KO GBIYANJU
KI O RA ẸRỌ WA YI TI NJẸ:-




## SOLO COCOA SPRAYER

N220.00

Ti a fi nfin koko?
Bi o ba ti ni eyọkan rẹ,
Owo tabua ti de fun ọ!
Bi awọn ẹrọ re ba nyọnu pupọ,
Kini ṣe ti o ko maa lo
Ẹrọ JLO?
Ko si ibikeji ẹrọ na ni Naijiria.
O rọrun lati lo
O si rọrun lati tunṣe
Nitoripe eroja ẹrọ na wa
Ni olu ile iṣẹ wa

OWO RẸ KO PỌ N220.00 PERE NI

Ma jafara, mu owo lọwọ ati Imọlẹ Owurọ kan ti a polowo ẹrọ yi si ninu ki o si maa bọ taara si:

WENTEC 1955

**Western Nigerian Technical Company Limited**

P.M. B. 5148: PHONE 22361/2
DUGBẸ ONIMATIRẸSI, IBADAN.


Printed and published by the People's Star Press Limited, N4/4968 Yemetu Aladorin P. M. B. 5230, Ibadan. Olootu (Editor) Lawuyi Ogunniran. E4/803, Aperin Adekile Ibadan. Lagos Office 18, Odunlami St, Phone 27017